# Joseph Edet Di Oga Agba Awon Omo Ogun Oko Oju—Omi

Laipe yi ni Ogbeni Joseph Edet Akinwale Wey di eni akoko ninu omo ile Naijiria ti yio koko gba ipo Oga agba ti ndari awon omo Ogun oju-omi ti ile Naijiria

Ogagun Joseph Edet Akinwale Wey bere ise Oludari agba omo Ogun oju omi ti ile Naijiria ni ojo kerinlelogun osu keta odun yi gegebi enikinni ti yio gba ipo Oga agba Oludari awon omo Ogun oju omi ti ile Naijiria.

Abi ogbeni Wey ni Kalaba ni ojo keje osu keta odun kerindinladota, awon obi ogbeni Wey ni Ogbeni Akinlaja Wey ati Iya Arit Ekpo ni asiko ti ogun agbaiye akoko fe lo si opin. Ni igba na ni die ninu awon enia ile Naijiri si ni anfani lati ma ran omo won ni ile eko. Ogbeni Wey si je okan ninu awon omo to se ori rere lati la ko eko labe awon ojise Olorun to wa si ile wa ni gba na.

Ogbeni Wey si bere ile eko alako bere ni Anua, ni agbegbe Uyo ni iha Ila Orun Naijiria ni odun 1930 Lehin na ni bi nkan bi odun meje sii o si lo ile eko ti Sacred Heart ni Ikot-Ekpene ati ile eko giga ti Sacred Heart ni Kalaba ti o si geye abayori eko re ni odun 1938.

Ni akoko ti Ogbeni Wey wa ni ile eko gbogbo awon awon eko nipa itan ti o ko ni igba na si je ti gege bi

Wo oju ewe karun




Our tradition is based on principles of lasting validity: Quality in every detail, true craftsmanship applied to most advanced production methods, safety and elegant styling. The scrupulous application of these principles in the design and manufacture of all Mercedes-Benz products is manifest in the product's performance and beauty. Mercedes-Benz vehicles of today are the embodiment of a 75-year tradition of progressive development in every sphere of car design and production.



MERCEDES-BENZ

DON'T FORGET THAT YOU CAN ALSO TRADE IN YOUR OLD MERCEDES-BENZ OR RENAULT CAR!

LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.

# IWE SI OLOTU

## Iwe Irohin Imọlẹ Gbayi Ni Ilu Ibadan

O tọ, o si yẹ ki nsọ fun araiye gbo iru iyi ati ẹyẹ ti Iwe Irohin Imọlẹ gba ni Ibadan lẹnu lọlọ yi, awọn kan nparọ fun wa pe Imọlẹ Owurọ ati Irohin Imọlẹ ọkanna ni wọn, ati ra irakura, ki a to mọ wipe ọti yatọ fun ẹmu, o ti re kọja.

Bi a ti nka ninu iwe nyin lojojumọ ti awa na paapa ṣe akiyesi ari wipe, iwe Irohin Imọlẹ Ọmọ niwọn, ṣugbọn Imọlẹ Owurọ ṣe lo ri fẹnfẹ-fẹnfẹ bi iwe ipẹjọ atijọ.

Iwe Imọlẹ Owurọ ẹlẹkẹ ecbu ni, a bu ni bi eni la u y i n, a sowo ete mọ kuta, ṣugbọn irohin Imọlẹ o jẹ iwe ti nkọ wa ni ọgbọn ati oye.

Gbogbo awọn arosọ inu rẹ ni o dara ti a si ngbadun rẹ. Iwe Irohin Imọlẹ ta ju akara gbigbona lọ ni Ibadan.

Mo ki Olotu pe o ku iṣẹ ati awọn asomọgbe rẹ.

Emi ni,
Johnson

IBADAN

## A r ẹ m u Erin Nkọ?

Olotu, ẹdakun ẹgba mi ni aye diẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ ti nkọ wa ni ọgbọn ati oye, ti o ntumọ-Yoruba fun w a dada, k o s i ẹniti yio ma ka iwe yin ti inu rẹ ko ni dun fun awọn ẹkọ inu rẹ.

Awọn ọrẹ mi ma wa gba iwe Irohin Imọlẹ temi ka ni, nigbati wọn ti mọ adun ẹ, nse ni awọn na nra ti wọn

Ọtito ọjọ mẹta ti ati ka ọrọ ọgbẹni wa Arẹmu Erin bẹni emi ngbadun gbogbo awọn ọrọ tio ba so ninu iwe nyin ọrọ rẹ ama dawa laraya tia ba nka

Inu mi yio dun ti nba mọ ibiti o ngbe awọn ọrẹ mi ati emi ni a nfẹ mọ ri ọwọ rẹ ka bi ẹmeji lọsọsẹ ni tabi ẹkan lọsọsẹ ni afẹ ma ri ọwọ rẹ

Nigbati a ko ri Ẹfufulẹlẹ ẹnikan bere ninu iwe nyin lọjọ keji si ẹkẹta ni ari ọwọ rẹ nitorina nibo ni Arẹmu wa.

Afẹ ma gbadun Arẹmu Erin pẹlu Anti Eji ni ẹkọọkan,

Mo dupẹ pupọ lọwọ Olotu.

Emi ni,
Tijani,

OKITIPUPA.

## Ẹ Jẹ Kani Irẹpọ

Olotu, ẹ gba mi ni aye lati ba awọn ọmọ iya mi sọrọ ti o dun mi lọkan, nitoripe ẹtẹ awọn na ni ẹte Ogbẹri, o yẹ ki a mura gìrigiri si idagbasoke ilu wa, ko yẹ ki a ma tiju ni akoko ti a wa yi.

Ẹ jẹki a pe aro ati ọdẹfin inu wa ki a ba ara wa sọrọ atata, ki a tete pa keeta ti si ẹgbẹ kan ki olukuluku wa ma wa ilosiwaju ilu wa, gbogbo awọn ti koto bi to ilu wa ni o gbaradi fun ida gbasoke ilu wọn.

Ẹ jẹki a sowọ pọ ni ilu wa ti o ba dara fun ẹnikan. o jọ dara fun gbogbo wa, ki a fi ti ẹnikan ki ṣe ti ọmọ iya mi, nitorina asiko ti a nya ara wa sọtọ ti kọja.

Eleyi ọmọ wa, tọhun ara wa ko ṣe iṣẹ rere kankan rara, a fi ki a mu ara wa ni ọkansoso iyẹn ni a to le gbadun aye wayi.

Ati ọmọ ẹgbọn ati ọmọ aburo, ẹ jẹ ki a fa ara wa mọra, ki a ni ifẹ si ọmọnikeji wa,

Olotu, ajinde ara yio maa jẹ.

Emi ni,
Lasisi

OKEHO.

## Ẹyin Ọba Ẹ Ma Dakẹ

Ẹ gba mi laaye ninu iwe Irohin Imọlẹ lati kesi gbogbo awọn Ọba ati Ijoye ti owa ni Iwọ Orun Najiria ki nwọn tete dide si ọrọ ti nja ranin-ranin nilẹ ninu ẹ g b ẹ ọmọ Oduduwa, bi oti bẹrẹ ni ọdun ni yi.

Ọlọla Akinọla Maja ni on da Akọwe agba ẹgbẹ ọmọ Oduduwa duro, apọn Igbimọ alabẹsekele ẹgbẹ na ni fun ọrọ anikan ṣe ti Oloye Maja ko fi lọ awọn nitorina awọn yọ ni baba ẹgbẹ.

Mo bẹ ẹnyin Ọba pe, ki ẹ ma fi ọrọ si abẹ ahọn mọ Olori ni ẹ jẹ ni ọtẹ yi, mo fẹ ki ẹ rọ oju abẹ niko.

Ki ẹ tete dide si ọrọ yi ki o to ju bayi lọ. Ẹnyin ni a fi ṣe Olori wa, ẹnyin ni baba wa.

Mo dupẹ Olotu fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni,
Kelani

ABẸOKUTA.

## Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ni ọjọ kẹta ẹṣu karun (3/5/64) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Bamgbose Street Eko.

Ao si tun fi tayọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titun ti nwọn ba wa si ipade lati jẹ ọmọ ẹgbẹ.

Ki ẹ tete de o.

LATIFU BABALỌLA
Adele Akọwe

BI O BA NI
**Iwe—Titẹ**
*FUN*
**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**
*ATI*
**Iwe Igbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ ERỌ—ITẸWE
**Modupẹ Printing Press**
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.
KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
*OWO PỌKU NI A SI NGBA*

IROHIN KO TO AFOJUBA
*Dan wa wo lẹẹkansoṣo ki o si ri iyatọ*

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI NWỌN NPE NI- Eleyi yatọ patapata si awọn Rọbi-rọbi. Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA' bi Mọna mọnọ

**RICHALET**

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO




Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nti kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di o w o Iyẹn ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni lẹ yi,

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba wọn yẹn a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Iatambulu si Itali jẹ

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se o, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọba, arun Ẹdọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa Egbogi-Amodi Apo ile ilọ, ẹhin didun tabi ibaradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa nba ẹjẹ ara rẹ patapata yio si n ẹjẹ rẹ mọ tonitoni pẹlu.

Ṣa dan igo rẹ ka o iwọ yio si ma a rohin rẹ fu mina pẹlu

Bere ni Ṣọbu awọn:—

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street ( Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji)

Adedun Chemist
14, Wakeman Street, Yaba

Ati ni awọn ṣọbu Ibadan:-
Iṣẹ Olodumare Dipensary Oke-Bọla

# Ọtẹlẹmuyẹ Nki Nyin O

Ọtẹlẹmuyẹ nki nyin o, ẹ ku lailai, ẹ ku atijọ, oju ti o ri nyin ma gbo? Ẹ ku ọ d u n, ẹ si ku iyedun, aṣe'yi ṣ'amọdun, ẹniti ko bi yio bi, ẹniti o bi yio tunla.

Ẹmi Ọtẹlẹmuyẹ Ọkunrin janinjanin iroko janinjanin ki gbogbo ẹnyin onkawe IROHIN IMỌLẸ nko da ẹnikan si. Mo si ki Olotu Iwe Irohin Imọlẹ paapa, Ọkunrin jẹjẹ abi'ja kankan gbogbo ẹnyin oṣiṣẹ Irohin Imọlẹ ni emi Ọtẹlẹmuyẹ ki porongodo pe, ẹ ku alaja ewu ọdun o.

Ki o ma ya nyin lẹnu pe, o ti to oṣupa mejilelogun ti ẹ ti gburo mi ninu iwe Irohin Imọlẹ gbẹhin, nko ku, bẹni nko si run; atijẹ atimu ti o dapọ mọ bukata ile ni ko jẹki nraye kowe sinu Irohin Imọlẹ mọ, ṣugbọn lagbara Oluwa ẹ o ma ri ọwọ mi ni ọsọsẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ.

Ọrọ ẹnu Ọtẹlẹmuyẹ ti ẹ ti nka tẹlẹ ri, ni ẹ ri ti ẹ nwi nisisiyi mo ti de Sokoto, mo ti de Safara, mo ti tatapo yọ si ilẹ Aganin, afẹsẹpa ni Agbadarigi ilu awọn Egun, eyi jẹki ngmu lẹnu bi abẹ, mo sọrọ titi ni Ile-Iwo! Ọmọ Odo-Ọba nwọn fun mi ni Wundia ẹlẹyinju-ẹgẹ, ọloyan gogo ogo, mo sọrọ titi ni Nguru nwọn f'ẹsin funfun balau ta mi lọrẹ.

Enyin onkawe Irohin Imọlẹ, ẹ ko ha ri pe, ọmọ sọrọsọrọ ni emi Ọtẹlẹmuyẹ iṣe? Fọ – pa wọn ni ọrọ mi isisiyi nitorina, ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ, ẹ ma a tọju kọbọ meji nyin silẹ lati fi ra IROHIN IMỌLẸ.

Ọtẹlẹmuyẹ nki nyin o, oju ko ni fẹ'raku o, lọsẹ to mbọ lagbara Oluwa, ngo kọlu Aṣẹwo Onipangbe.

# ★ YẸ IRAWỌ RẸ WO ★

**AQUARIUS** (Jan. 20-Feb. 18) Nṣe ni ki o foriti i ki ọrọ o ṣe o w o ko ṣe owo ti o m b ẹ nilẹ ba le yanju lati ọdọ ẹnikan ti o m b ẹ ni okere, ọjọ o n i dara lati sa pejọ.

**PISCES** (Feb. 19-March 20) Maṣe gbe ọrọ ti ko ni lati si ọkan lati mọ fi huwa, b i k o ṣ e ki o ma huwa jẹjẹ, owo pupọ yio t ẹ ọ lọwọ lati ma n a iwọ yio si ri owo fi dara.

**ARIES** (March 21-April 19) Iwo yio r i a w ọ n isoro ti o ti nse idina fun ọ lati ọjọ yi wa, ma si ṣe lẹnu nigbati awọn eaia meji ba mba ara wọn ṣẹnu. Awọn ọrẹ yio tẹ ọ lọrun loni

**TAURUS** (April 20-May 20) Otutu aburadı kan ti ko iṣe ododo yio mu ọ latari ọrọ kekere kan. Maṣe dasi ọrọ na. Arisiki yio bo ọ tobẹ ti iwọ y i o firi ere jẹ. Ṣe faji lọ sode loni tabi lọ sile awọn ọrẹ r e

**GEMINI** (May 21-June 21) Irenu yio desi ọ loni, ara rẹ yio si balẹ. Awọn ọrẹ rẹ y i o ṣe iranwọ fun ọ lati bori isoro gbogbo ati lati ṣegun ọta. Oni dara lati kọwe si idalẹ.

**CANCER** (June 22-July 22) Ọjọ rere ọjọ irọrun ni oni jẹ fun ọ gbidanwo lati pari awọn ọrọ ija ti o ti wa nilẹ, lọ wo awọn ọrẹ rẹ nile wọn. Ija kan yio bẹ silẹ loni lati ọwọ eniti o fẹran.

**LEO** (July 23 - Feb 22) Ṣe ohun ti o ngbero lọkan lati ṣe, ọjọ oni dara fun irinajo ti o fẹ rin lati lọ ṣe abẹwo ẹni nla kan, gba imọran tẹlomiran nipa awọn ija ti o wa larin ẹbi rẹ.

**VIRGO** (Aug. 23 – Sept. 22) Bi o ti wu ki o ri alafia ni ọjọ oni yio jẹ fun ọ. Ti ara rẹ ni ki o mu ranloni Maṣe lọ sibi ti o lariwo loni, owo yio tẹ ọ lọwọ loni.

**LIBRA** (Sept 23 - Oct 23) Ọrọ ara rẹ ni ki o ran loni, Ipade oni yio larinrin, awọn ọrẹ yio ma fẹran rẹ pupọ, Maṣe da ejọ ti iwọ ko mọdi.

**SCORPIO** (Oct 24 – Nov 22) Onilati kọkọ dubulẹ ki o sun ki iṣẹ ti o fẹ ṣe le yanju kedere, Ọrọ kan wa nilẹ ti o nru ọ loju tun ọrọ na yẹwo lati ipilẹṣẹ.

**SAGITTARIUS** (Nov. 23 - Dec. 21) Ara yio ro ọ wẹsi, gbogbo iṣẹ ti o wa niwaju rẹ ni iwo yio yanju kedere, ṣugbọn maṣe fi iṣẹ pa ara rẹ lori, jẹki ẹlomiran ran ọ lọwọ nipa rẹ.

**CAPRICORN** (Dec 22 – Jan. 19) Arẹ yio mu ọ, maṣe yan iṣẹ fun ara rẹ pupọ, Tọju awọn ẹbi rẹ, ilọsiwaju yio si ma de ba ọ lẹnu iṣẹ rẹ na.


# EGBOGI JẸDIJẸDI

BERE EGBOGI



## "CYCLOVEN"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara rẹ si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu" tabi Iho idi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnse. Arun Jẹdi ẹdi je ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri lode nisiyi ti w n a ma po owo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la leri mẹwa ninu ọgọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe bọya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara. Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakana. Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa alko mẹ ṣe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ, ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pẹlu lojoujmọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu, pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Ṣuga tabi oniruru ohun adidun pupoju nigbakugba, Jẹdijẹdi orişirişi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ ade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnsẹ, tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnṣẹ tan ni, tabi ti nrin ọ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egboogi "CYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani ṣẹṣẹ wa idi rẹ ki o si danwo orisi meta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alafia yio de si ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogid taa igboro ilu Naijiria jakejado. Bere rẹ ni:

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)



# IWE ITUMỌ ALA

Josefu Alala ti ẹ ti nkan ninu iwe Irohin Yoruba ti jade ni odindi fun tita nisisiyi.

OHUN TI OWA NINU IWE NA

1. Egbogi Ajẹbidan agbabiẹtu.
2. Odu Ifa merindinlogun lati ma a fi yẹ itumọ ala rẹ wo
3. Ẹnikẹni ti o ba ra iwe yi ni anfani lati bere ala rẹ nigba gbogbo lọfẹ lọwọ Josefu Alala.
4. Koiti si ikeji rẹ ninu iwe itumọ ala ti o ti njade ri nitoripe JOSẸFU ALALA ni o ṣe e

Tete ra tirẹ loni ki o to tan.

AKIYESI

A tun nfe asoju ti yio ma ba wa ta iwe na, owo pọọku ni ao ta fun wọn ki nwọn ba ri ere gọbọi jẹ ti o ba fẹ se asoju wa kọwe fun iwe adehun,

Iye owo 5/- £2

**J. O. Shoyinka**
N2/99 Shittu Street
Ibadan

tabi ni
1, Isiba Street Odo Ẹran
Itirẹ Suru—Lere

## Joseph Edet Di Oga Agba Awon Omo Ogun Oko Oju-Omi

Lati Oju Ewe Keji

awọn oni ṣe Ọlọrun ṣe wa si ilẹ Naijiria gẹgẹbi Mungo Park, Clapperton, David Livingstore ati bẹẹbẹ. Eleyi si mu ki Ọgbẹni Wey si ni Ifẹran nipa irin ajo loju omi.

Gẹgẹ bi o si ti kuro ni ile ẹkọ ni ti nṣe iṣẹ ni ile iṣẹ ti igba lailai ti Marina gẹgẹbi o ṣiṣẹ kekere ninu Ọdun 1939.

Fun bi nkan bi ọdun mẹwa si Joseph si mura pẹlu ifarada lati ma ṣe iṣẹ a ti pe ko si ni ireti pe on le di Olori ogagun oju omi ti ilu on lasiko yi ati pe on le jẹ ẹni akoko ti yio wa ni ipo giga na.

Lati igba na ni ifarada ati emi ẹkọ kikọ ninu Ọdun 1949, a yan Ọgbẹni Wey lati lọ fun ẹkọ kikọ ni ilu Gẹẹsi. Ọgbẹni Wey si lọ ile ẹko giga fun ọkọ oju omi ni ile ẹkọ giga ti London County Council, School of Technology ti o si pada, si ilẹ Naijiria ni Ọdun 1950 nigbati o yege ninu ẹkọ rẹ.

Ni igba na ni ọrọ oṣelu si nda gba sii ni ilẹ Najiria ti awọn igbimọ ti ile aṣofin si ṣe ofin gẹgẹ bi awọn Ọmọ Naijiria yio ṣe wa ninu awọn Ọmọ Ogun oju omi ti ile Naijiria Ni akoko eyi Ọgbẹni Wey si wa gẹgẹbi oṣiṣẹ ọkọ oju omi ni Ọdun 1958.

Lẹhin eyi, o tun ni anfani ẹkọ miuran ni ilu Gẹẹsi ni ile ẹkọ kan na ni ibi ti o ti lọ kọ ẹkọ tẹlẹ ni London County Council School of Technology fun ọkọ oju omi, o si tun pada si ilẹ Naijiria ni Ọdun 1959 nigbati o tun gẹgẹ ninu ẹkọ rẹ ti o si wa ni ipo ekinni ninu oṣiṣẹ ọkọ oju omi, o si tun ṣe iṣẹ ninu ọkọ oju omi kan ti a npe ni "Pathfinder" ti o si jẹ ọkan ninu ọkọ ti ilẹ Naijiria.

Gẹgẹbi Ọgbẹni Wey si ti fi arada ti o si nṣe iṣẹ rẹ pẹlu irẹlẹ, nigbati o di aseko ti ilẹ Naijiria fẹ gba ominira ni Ọgbẹni Wey gba ipo gẹgẹbi oṣiṣẹ agba ninu ọkọ Ọmọ Ogun ti Naijiria gẹgẹ bi igbakeji Ọga Ọmọ Ogun Naijiria.

Nigbati odi Oṣu kẹwa ọdun ti orilẹ Naijiria fe gba ominira ni Ọgbẹni Wey si tun di ẹniti yio wa ninu Ọkọ ti anpe ni H. M. N. S. "NIGERIA" ti o si di ọga agba ninu Ọkọ Ọmọ ogun ti Naijiria.

Ninu ọdun 1962 Ọgbẹni Wey si jẹ Ọga ninu awọn ọmọ ogun oju omi ti ile Naijiria ti o si jẹ alakoso H. M. N. S. Beecroft fun ti Apapọ ti awọn Ọmọ ogun oju ni Apapa. Ninu ọjọ kedogbọn Oṣu kẹfa Ọdun 1963 ni o tun di adari ọkọ oju omi.

Lẹhin ti Ọga agba t o jẹ oludari awọn Ọmọ Ogun Oju omi ti ilẹ Naijiria Ọgbẹni Kennedy fẹ fi iṣẹ na silẹ fun isimi ni Ọgbẹni Wey si ropo rẹ ti o jẹ Ọmọ ile Naijiria akokoyi ni ti yio gba po ca.

Ninu ọdun 1963 o si lọ Holland gẹgẹbi aṣoju ijọba Apapọ lati ṣe ibẹwo ọkọ oju omi kan ti a npe ni "OGOJA" lati lọ jiroro fun gẹgẹbi ọkọ oju omi na yio ṣe de ile Naijiria pẹlu awọn Ijọba ti ilẹ ilu Dutch. Ọgbẹni Wey si tun rin irin ajo nipa ilọsiwaju awọn ọmọ Ogun ti ilẹ Naijiria larin oṣu ekinni si ẹkẹta ọdun lọ si Idian. Ọgbẹni Wey si tun pẹlu awọn ọmọ ilẹ Naijiria to tun lọ si ilu okere fun ilọsiwaju ọmọ Ogun ọkọ oju omi.

O si tun ba alakoso Ijọba Apapọ ti nbojuto awọn ọmọ Ogun oju omi ti Naijiria Ọlọla M. T. Mbu lọ si Amsterdam, Holland lati lọ gba Ọkọ oju omi ti anpe ni "AGOJA" ati fun igbimọ ti a npe ni Organisation of African Unity ni Accra, Ghana ninu ọdun to kọja.

Ọgbẹni Wey si tun sọ ninu ọrọ rẹ fun Onirohin wa pe ninu Ootọ ati Ododo ni on yio wa titi on yio fi ku ati pe on si fi ri ipọnju ati pe on si fi ara daa.

Ọgbẹni Wey si tun sọ si i pe on ranti Ọgbẹni F. W. Skutil ti o ti jẹ Oludari ọkọ oju omi atipe on na lo si ṣe ilana nipa awọn ọmọ ogun oju omi pẹlu Ọga agba tẹlẹ Ọgbẹni Kenedy ti o tun ṣe ọpọlọpọ iralọwọ gẹgẹ bi iṣẹ awọn ọmọ ogun na yio ṣe yọri si rere.

Ọgbẹni Wey si tun sọ fun Onirohin wa pe on si ni ọpọlọpọ iṣẹ lati ṣe fun Ijọba Apapọ ilẹ Naijiria ati awọn enia ilẹ Naijiria nisisiyi ju bi o si ti wa tẹlẹ ri. Ọgbẹni Wey si tun sọ pe on yio ri mọ pe on sa gbogbo ipa on lati le jẹ ki ilọwaju wa ninu awọn ọmọ Ogun oju omi Naijia.

Ọgagun Wey ati Iya afin Anne Bassey Wey bi ọmọ mẹrin, Ọkunrin si jẹ meji Obinrin si jẹ meji.


## Ikoosi Ikọ Ti Ọjọ Rẹ Ti Pẹ Lara

Pupọ ninu awọn egbogi rọbirọbi ti wọn npolowo ti wọn si nta kakiri igoroiju Eko ati ni igbereko ko ni ṣe iwsan wọn lailai afi ki o ri ojulowo haunhaun atamase egbogi ti o laabara gidigidi ti o le ṣe iwosan rẹ titi de inu ifun ati igb-aya ti yio mu ọ ma tu "Ikọ" mọ bi kẹlẹbẹ jade ti o ba rhu ẹ titi yio fi tan ni inu rẹ qatabata. Awọn ikọ miran wa ti o dabi ẹnipe wọn ama la ogun tabi orişirişi egbogi tabi ti o ba jẹ pe bẹni, agba ọ ni imọran wipe ki o ma lo egbogi awon ara ilu Abyssinia ti nwọn npe ni "Etibard" pẹlu egbogi ti o ba amu

PORAL TABLETS
THIOLYPTINE SYRUP
THYMO-EPHDRIN LINITUSS
ETIBARD ABYSSINIA POWDER

Fun iwosan ikọ Asima, ikọ fere ikọ otutu igba-aiya ikọ gbẹdu, ikọ-ọnafun, ikọ-gbigbe tabi eyiti o ma nmu ki enia ma ha ọna ọfun tabi pẹlu kẹlẹbẹ tabi ti o ma njẹ ki nia ru nipa wahala tabi aikoni le sun daradara lọsana ati loru-gbiyanu lati dan ọkan ninu awọn egbogi alagbara idigidi wọnyi wo fun ara rẹ iwọ yio si ri iyatọ gburugburu larin wọn si awọn olomi ṣorokiti ti wọn nta kakiri

O daju nibẹ iwọ yio bẹrẹ si ri alafia, iwọ yio ma ṣeun daradara wasi ma sun fọnfọn pẹlu Alafia de si ọ ni yen Bere egbogi ajẹbina y ni ṣọbu awọn:—

Waterloo Medicine Store
8 Plamchurch Street, Lagos
Phone:–22878 ,Nigeria, (Ọja ita Faji)



## Iwọ Ha Nlọ Si Mẹkka Ni Ọdun Ti nbọ Bi?

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA"
MO JẸ RI O, OLUWA MO JẸ IPE RẸ
ẹnikẹni ti o ba fẹ lọ si "MẸKKA" Ilu Mimọ ni ọdun yi gbọdọ ni iwe

"AFINIMỌNA NPA ISIN HAJI"
LỌWỌ KI OLUWARẸ MA BA ŞINA TABI NA OWO INAKUNA. KI O LE LỌ ALỌBỌ MẸKKA NA DADA
t'Oluwa jọwọ ṣe Isin Haji wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ fun wa ni rere ti aiye ati t'ọrun Oluwa wa, ki o sisọ wa ni bi iya nitori IWỌ NI ỌBA alagbara Olubor gbogbo ẹda patapata" Amin·

**"WAS SALAM"**

*AKIYESI* Gbogbo Musulumi Ododo ni oyẹ ki o ni na lọwọ nitori igbati yio ba fẹ lọ si MẸKKA
*Iye Owo 5/6, £3 fun dosini*

MANAGER
N2/99 SHITTU STREET
Ibadan


## E ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ

IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE. TENI GBOGBO LAWA

No. 591  TUESDAY, APRIL 28, 1964  (2D)

## Ẹgbẹ Afẹnifẹre Ṣe Ipade

IBADAN: — Gbogbo ile lo kunsọsọ ti ẹsẹ ko si gba ero fun Ogunlogọ awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) ti nwọn ṣe ipade Igbimọ alaṣẹkele kan ni abẹ alaga Alhaji D. S. Adegbenro ti iṣe Asiwaju ẹgbẹ Afẹnifẹre ninu ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni ọjọ Abameta ti iṣe ọjọ kẹdọgbọn oṣu yi.

Irohin fi ye wa pe gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na ti nwọn jẹ Igbimọ ni nwọn ṣe ipade na, gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ti nwọn gbọ ti nwọn si lọ, ṣugbọn ti nwọn ki iṣe ọmọ ẹgbẹ Igbimọ, ti nwọn ko si fi iwe pe, nwọn ko gba wọn laye lati wọle.

Oniwe irohin wa ti o wa ni Ibadan fi ye wa pe, nwọn ko gba awọn oniwe irohin laye lati wọle, ṣugbọn agbọrọsọ awọn ọmọ ẹgbẹ na fi ye wa pe, ọrọ pataki ti nwọn sọ ninu ipade na ni ti aṣepọ ẹgbẹ Alakukọ ati ẹgbẹ Afẹnifẹre.

Ohun miran ti a tun gbọ pe nwọn sọrọ le lori ibo atundi si ile Igbimọ Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ati ti ile Igbimọ Aṣofin Apapọ Ijọba Naijiria eyiti nwọn sọ pe, nwọn o ṣe laipẹyi.

A gbọ wipe, eto nlọ ni abẹlẹ, nipa ibo atundi ni Ipinlẹ na nwọn le tu ile Igbimọ ka, ki nwọn pe fun ibo atundi nigbakigba lati isisiyi lọ.

# IGARA OLỌṢA KAN WẸWỌN ỌDUN MEJI

APAPA-AJEGUNLẸ :- Gbogbo ile ẹjọ lo kun ṣọṣọ ti ẹsẹ ko gba ero nigbati awọn Ọlọpa mu igara Ọlọṣa kan, Johnson Imori, eni ọdun medọgbọn wa siwaju adajọ Agba ile-ẹjọ kekere Apapa Ajegunlẹ fun ẹsun ole jija ati ile fifọ ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu yi.

Ọlọpa ti o ba ọdaran na ṣejọ ni kotu ṣe alaye fun Ile ẹjọ pe, ninu oṣu kọkanla ọdun ti o kọja yi ni ọdaran na lọ fọ Ile itaja ogbẹni Ahmed Shashima

Nigbati ọdaran na fọ Ile itaja na tan, o wo gbogbo inu ile, o si gbe gbogbo awọn aṣọ ti o wa ninu ile itaja na ti iye owo wọn jẹ pọnun merindin-la-dọsan ati sisi ('£166 : 0 : 6d)

Ṣugbọn nigbati ọdaran na ko ẹru na tan ti o si ko wọn lọ, ni ọwọ awọn ọlọpanu ba tẹ, nigbati nwọn si bi lere pe, "Nibo ni o ti ri awọn ẹru wọnyi ?" Ọdaran ko le da wọn lohun, ni nwọn ba mu ọdaran na lọ si Teṣan.

Ṣugbọn nigbati nwọn yio fi de Teṣan Ọgbẹni Ahmed Shashimi ti de Teṣan lati wa sọ fun awọn Ọlọpa pe, awọn ọlọṣa ti fọ Ile itaja on, nwọn si ko awọn aṣọ ti on nta lọ.

Nigbati awọn Ọlọpa si ko ẹru ti awọn gba lọwọ ọdaran na han Ọgbẹni Ahmed pe, njẹ o mọ eniti o ni awọn ẹru wọnyi, Ọgbẹni Ahmed gbọ wipe awọn ẹru ti ole ko lọ ninu Ile itaja on ni awọn ẹru na.

Nigbati adajọ gbọ ọrọ yi ti o si ri awọn ẹru aṣọ na ni o ba ṣe idajọ pe ki ọdaran na lọ fi ẹwọn oṣu meji jura tabi ki o lọ fi igba pọnun (£200) tanran si kotu.

Ṣugbọn igara ọlọṣa na sọ fun adajọ pe on ko jẹbi awọn ẹru aṣọ na ti on jiko.

# Omiṣade Ko Lọ Si Ikẹnnẹ

### Lati Oju Ewe Kini

ọrọ rẹ tan, ni Adajọ Agba Ọlọla Louis Mbanefo bere lọwọ Ọdẹsanya pe, "Nwọn ti fi ofin pajawiri gbe, ki awọn Ọlọpa to mu tabi nwọn ti mu tan ki nwọn to fi ofin pajawiri gbe ?

Ṣugbọn Ogbẹni Adebiyi ko jẹki Ọdẹsanya dahun ibere na ti o fi sare dide ti o si sọ wipe,

Ibere ti adajọ mbere yi wa ni oju ewe iwe ọgọta (page 60) Ogbẹni Ọdẹsanya si ka ọrọ na ti o ka bayi pe

"Bi mo ti mbọ, ni mo pade Ọga Agba awọn Ọlọpanu, Ọgbẹni John Lyni loju ọna ti o si yọ iwe sagila kan jade ninu apo rẹ, eyiti nwọn ti kọ oruko mi si pe, nwọn ti fi ofin pajawiri gbe mi gẹgẹbi ofin Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria."

Ogbẹni Ọdẹsanya wa ṣe alaye pe ofin pajawiri ni nwọn kọ fi gbe ki o to wa di wipe nwọn tun mu fun ẹsun iditẹ si Ijọba.

IGBOKEGBODO

Lẹhin eyi ni Ọgbẹni Adeyiga Akinsanya wa bere pe, "ee ṣe ti ẹ fi ragabu mi?" Ọga awọn Ọlọpa si sọ fun pe, nitori gbogbo awọn igbokegbodo rẹ nipa ẹkọṣẹ Ogun ni Ghana ni.

Ọgbẹni Ọdẹsanya pari Ọrọ rẹ lori Ogbẹni Adeyiga Akinsanya, o wa lọ si ori ẹjọ ti Ọgbẹni Gabby Shasọrẹ eni ti o ṣe apejuwe rẹ gẹgẹbi ọkan ninu awọn Ọjọgbọn imọjinlẹ nipa iṣiro owo ti o nṣiṣẹ fun ẹgbẹ Afẹnifẹre.

Ogbẹni Ọdẹṣanya tun ṣe alaye pe, adajọ si ararẹ lọna nigbati o sọ wipe, Ṣasọrẹ lọ si Ikẹnnẹ lati ba wọn lọ pin awọn ohun ija Ogun, eyiti awọn kan fẹ fi gbe Ogun ti Apapọ Ijọba Naijiria



Lateef JAKANDE

Ọgbẹni Ọdẹsanya se alaye fun ile ẹjọ pe, ko si enikan ti o sọ ninu ile ẹjọ na pe awọn ri Shasọrẹ ni Ikẹnnẹ, ko si ba wọn pin nkan ija ogun.

AWỌN OLOYE

Bakanna ẹwẹ, ko si ẹniti o ri ibọn ati ọta ibọn lọwọ rẹ, bẹni nwọn ko sọ fun ile ẹjọ bẹ pelu.

Ọgbẹni Odẹsanya ṣe alaye pe, Ọgbẹni Ṣasọrẹ ṣe akiyesi pe iṣẹ awọn ti awọn jẹ Oloye ninu ẹgbẹ Afẹnifẹre lọle julọ. Bi ẹnikẹni ba si fẹ ni anfani kan lati da aabo bo ara rẹ, o ni awọn Oloye ẹgbẹ na lo tọsi, nitoripe oju awọn nri mabo bi awọn ti nlọ jakejado Orilẹede Naijiria, ohun ti oju awọn nri o gba yẹkẹtẹ.

Nitori idi eyi, awọn enia na ṣe alaye pe o ye ki awọn ni igboiya die lati le ma ṣiṣẹ awọn laifoiya ati laiberu ki awọn o le duro



Ogbẹni Olawọyin

digbi.

O wa ka lati ẹnu iwe ẹjọ ti awọn enia na ro niwaju adajọ akọkọ pe, ko si Ṣhasọrẹ ni ibiti nwọn ti npin awọn nkan ija ogun.

Nigbati o di agogo kan kọja iṣẹju mẹdogun ni ọgbẹni Ọdẹsanya bẹrẹ ẹjọ ti Ọgbeni Omiṣade, o si da ọrọ rẹ duro lori ọgbẹni Omiṣade ni deede agogo kan abọ.

Ṣugbọn yio tun man ba ọrọ rẹ lọ niwaju ijoko awọn adajọ na ni owurọ yi.

Printed and Published by Modẹpẹ Printing Press 16, ... Street Lagos Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadir Street (C. M. S. Grammar School) Bariga 28/4/64